21 AUG 1974

Kongi Nap WK 2
9 10 18

ASIKO Bks Wk 2
7, 12, 13, 14,

ROSS BKS Wk 2
35x30

# Imọlẹ Owurọ

Ẹṣin Ọrọ Wa: "IMỌLẸ DE! OKUNKUN PARADA"

UNITY NAPS
For 3 sure draws in Wk 3 try to see The Manager Unity Pools House, E4/226, Gbelekalẹ Ibadan.
See him with ₦5 before 9 p. m. on Friday.
**1, 10, 28**

Independent Paper VOL. XIII No 651 SATURDAY AUGUST 10 — FRIDAY AUGUST 16, 1974 5K. (KỌBỌ MARUN)

# 'ỌMỌ SUN OKU BABA RẸ NINA'

AWỌN Afẹsunkanni ti fa ọkunrin Agbẹ eni ogoji ọdun kan wa sile ẹjọ Magistrate ilu Ilọrin lati koju ẹsun pe o lu baba rẹ pa.

Ọkunrin ọdaran na ni orukọ rẹ njẹ Amọdu Adebayọ Sule ti abule Marafa lẹba Oke-Oyi ni igberiko Ilọrin.

Niwaju ile ẹjọ na l'abẹ Adajọ Ọgbẹni M. A. Awolabi ni nwọn mu ọkunrin na wa. Ṣaji Ọlọpa kan Ọgbẹni Makama Agwai si ni afẹsunkanni ti o nka ẹsun si ọdaran na lọrun.

Nigbati afẹsunkanni na nka ọran si i lọrun, o ni ọrọ kan lo ṣebi ọrọ ni ọgbọnjọ oṣu keje ọdun yi laarin ọmọ na ati baba rẹ Alagba Sule Adelẹyẹ, ninu eyi ti ọmọ na ki baba rẹ mọlẹ, ti o na an ni inakuua nipa eyi ti baba na fi farapa pupọ. O ni nipa ina na ni baba yi fi ku.

Afẹsunkanni na sọ siwaju si i pe nigbati ọmọ na ri i pe baba oun ti ku, ni o ba tana ru ile na, ninu eyiti oku baba na tun jona di eeru.

Ẹwẹ, Afẹsunkanni na sọ pe lẹhin eyi ni ọkunrin na tun tana ru Mọṣalaṣi kan ti o wa lẹba ile wọn, ti apa kan Mọṣalaṣi na si jo pẹlu.

Afẹsunkanni na sọ fun ile ẹjọ pe ọdaran na nṣe eyi ki nwọn le sọ pe ijamba ile jijo l'o pa baba rẹ. Ẹjọ na nlọ lọwọ.

# Akirun gba Ajagungbade l'alejo

NI ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu keje ọdun yi ni Akirun Ikirun Ọba Lawani Adeyẹmi Oyejọla keji gba Ṣọhun Ogbomọṣọ Ọba Ọladunni Oyewumi Ajagungbade kẹta l'alejo ni aafin rẹ.

Ọpọlọpọ enia l'o pade rẹ laafin Akirun. Nigbati Akirun mu alejo pataki na yi aafin rẹ ka tan ni nwọn kọja si Gbọngan ilu Ikirun nibiti oniruuru ẹka ẹgbẹ Alafọwọsowọpọ mẹwa ti nṣe ipade pọ sọrọ.

LATI ỌWỌ LASISI OGUNṢỌLA, IKIRUN

Ninu ọrọ rẹ, Ọba Ajagungbade yin awọn ọmọ ẹgbẹ na fun ẹmi ifọwọsowọpọ wọn. Ọba na rọ wọn lati tẹra mọ ọgbin onjẹ ki iyan ma baa ṣe waiye ni ilẹ wa.

Ọba na fun wọn ni ẹbun Ogun Naira, o si ṣe ileri pe, oun r'a le di ọmọ ẹgbẹ laipẹ. Ọba na pada si ilu rẹ ni ọjọ na.

Eyi ni irinajo akọkọ ti Ọba na yio kọ ṣe si ilu miran lati igba ti o ti gori itẹ Ṣọhun Ogbomọṣọ.



AWORAN ẹgbẹ yi nṣe afihan Ọbabinrin ilẹ Gẹẹsi Alaiyeluwa Elizabeth keji, Baale rẹ ọmọ ọba Phillip bi nwọn ti nrin lọ tọwọtọwọ ninu gbọngan ile Ọlọrun George Mimọ ni ile ola Windson Castle nigba ajọdun ọdun idanilọla iru oye idanilọla ti o ga julọ ni ilẹ Gẹẹsi eyi ti eleegbe ọba Edward kẹta dasilẹ ni ọdun 1349.



## A! BABA MERO !!

A! ta leleyi o ? Ewo tun n'Imọlẹ Owurọ gbe wa yi o ? Oun ni OJO LADIPỌ, Alawada kẹrikẹri n'ilu Eko. (Woju ewe karun fun irohin.)

## Apprentice Wanted

LEARN to become a succesful printer. Learn on mordern marchine with modern technique.

Parents, don't waste the time of your fresh Primary six & mordern III school leavers send them to learn the art of modern Printing, Marchine operating, and Book - binding from us. Apply personally today.

The Works Manager,
(Imọlẹ Owurọ)
N4/696 Yemetu Aladọrin,
Ibadan.

ATIORO OMO ATIALA

## Mase fara we won [5]

Ẹ ma gbagbe o
Gbogbo jinmaa wa;
Ẹ je k'a ṣ ra faiye
K'a ma fara we wọn.
Ẹ jẹ ka bila f'aiye
K'a ma f'owa jọ enia
Nitori enia buru
Enia ko nilaari,
Ọmọ araiye buru
Bi a ba fara we wọn
O le fọn ni nikun.
Ẹ wo ọpọ enia
Ti mbẹ l'ẹwọn l'ode oni,
Ẹ wo 'ye ọmọ aiye
Ti mbẹ ni tubu Ọba,
Ẹ wo ọgọọrọ enia
Ti mbẹ l'ẹwọn
Ti nwo karo!
Bi a ba tan'di ọrọ wo
Ti a tan an yẹbẹyẹbẹ,
O da mi l'oju
Pe, afarawe ẹda
L'o mu wọn pọ nibẹ.




Ṣe b'enia ko ba ṣe ilara enia
Ko nii huwa aitọ.
Bi a ba duro de Ẹlẹda
A ko ni i ṣe 'lara ẹnikẹni
Bi a ba f'ọran mọ
Ọba Edumare
A ko ni i kabamọ.
Ṣugbọn ọpọ enia
L'o mbẹ ni dunia
Ti ko ronu rara,
To jẹ pe:
"Lagbaja lowo lọwọ,
Emi na fẹẹ lowo"
Ni nwọn mba kiri.
Ṣugbọn asẹhinwa, asẹhinbọ
Nwọn bọ s'oko abamọ;
Kaka ki nwọn lowo ọhu
Nwon a pada d'ẹni
Ti ntọrọ jẹ kiri
Nwọn a d'opijẹ l'aiye
Nwọn a d'ẹni itan.
Bi nwọn tilẹ ri
Owo l'ọna aitọ
Yio fo lọ nile wọn ni.
Orukọ wọn a bajẹ.
Igbẹhin wọn a balumọ;

Nitori o da mi l'oju pe
Ẹni t'o tori k'o le lowo
T'o np'ọmọ aiye lẹkun,
Enia ti nfẹ ẹ d'araba
Ti nṣe ẹgbe rẹ niku;
Egun kọ, epe kọ,
Ibi ni yio ṣẹlẹ
Lẹhin iruu wọn.
O da mi loju
Pe, enia ko ni i fi
Ika di ẹru
Ki o gun gẹgẹ;
O da mi loju
Pe, enia ko nii gbin
Alubọsa ko hu ẹf'...
Eni ba taja ẹrupẹ
Yio gbowo okuta,
Ẹlẹṣẹ ko si nii lọ
Lai jiya ẹṣẹ.
Nje gbogbo enia pata
Ti ngbọ nasia yi:
A nke lojoojumọ
Pe, ki ẹ ṣiwọ ilara ṣiṣe;
Ẹ ma ṣelara enia mọ
Nitori kadara
Ni nṣe lọran ọmọ enia
Enia kọ lo kọ kadara
Aala to da wa
L'o da akọmọ mọ wa.
Ilara ko ran an,
Ikanju ko ran an,
B'enia ti wu
Ki o kan Ẹlẹda l'oju to
Oluwarẹ ntan 'raa rẹ ni,
Ikanju ẹda
Ko le yi Aala l'ọkan.
Ẹ jẹ ki o lọọ ye nyin
Gbogbo ẹni ti ngbọ mi,
Pe, letoleto l'ọrọ Ẹlẹda
Akoko ati igba
Ni nṣe l'ọran ọmọ enia,
Ẹ jẹ ka na suuru si i.
A kii kanju tu olu ọran,
A ki i f'ikanju la ọbẹ
Ti nho ṣọṣọṣọ
A ki i f'ikanju re ida
Ti mbẹ l'ori ikọ,
Nitori bi a ba ṣe wọn
Nṣe ni i jajo ni l'oju,
Nṣe ni i yọ ni l'ẹnu.
Ani ẹ ma gbagbe o,
Pẹlẹpẹlẹ l'o l'aiye;
Pẹlẹ l'aa p'amukuru pẹlẹ,
Igba onipẹlẹ ki i fọ,
Awo onipẹlẹ ki i ya,
Ohun a f'ẹlẹ mu
Ko ni i bajẹ, o daju,
Ohun a f'agbara mu,
A maa le koko.
Ẹ ma gbagbe o
Ilẹ enia ni i ṣu
T'Ọlọrun Ọba ki i su;
Eda l'oju nkan
Oju ko kan Aala
L'Oke ọrun;
Ki i ku, ki i run;
Bẹẹni ire ko tan
L'ọdọ Aala
Ti i j'Ọlọrun Ọba.
B'o nṣe fun 'ya
T'o dabi ẹni pe
O f'ẹmọ rẹ silẹ,
B'o nṣe fun baba

T'o dabi ẹni pe
Ko ranti aya,
B'o nṣe f'aburo
Ti koi ṣe f'ẹgbọn,
B'o nṣe fun Taiye,
T'o ṣe fun Idowu
Ti Kẹhinde
Ko tii ri nkankan,
Ẹlẹda ko binu
Bẹẹ l'oore pọ lọdọ Rẹ,
Sa fẹdun rẹ le E lọwọ
Ki o si mu suuru si i
O da mi l'oju
Pe, yio ṣe tirẹ fun ọ
Nitori eesu enia
Ni i gbe, t'Aala ki i gbe;
B'oo ba r'ẹni
Ti nkanju ju Ẹlẹda lọ,
Jọwọ ma fara we wọn,
Nitori bi o ba kọ
Ti o ko gbọ 'mọran
T'o nta 'gbọn araa rẹ,
B'o ba yi ọ lọwọ,
Mase kesi mi.

ỌLỌLA ATIORO

# Omo-ale ni Egbon wa — Aburo

NṢE ni gbogbo enia ti o wa nile ẹjọ giga Ibinni kun fun kayeefi nigbati awọn ọmọkunrin kan fi ẹgbọn wọn patapata wa si ile ẹjọ na pe ki ile ẹjọ ba wọn so o l'ofin pe ẹgbọn wọn na ko lẹtọ lati role baba awọn nitori-pe "ọmọ ale" ni iṣe.

Ẹni ti nwọn pe l'ẹjọ na ni ẹni ọdun mọkandinlọgọta Ọgbẹni Idubor Ẹgbọn Esekure, ti o nṣiṣẹ awakọ, ti o si ngbe ni ọna Sakpoba nilu Ibinni.

Ninu ẹjọ ti nwọn pe na, awọn aburo rẹ sọ pe baba awọn ti sọ fun awọn ki o too ku pe Idubor ki iṣe ọmọ oun. Nwọn ni nitorina, ki ile ẹjọ so ọkunrin na l'ofin pe ko gbọdọ fi aran rẹ pe ọmọ baba awọn mọ, kọ gbọdọ pin ninu ogun baba awọn, bẹẹni ko si gbọdọ role baba awọn.

IDAJỌ

Ṣugbọn ninu idajọ rẹ l'ori ẹjọ na, Ọlọla Rufus A. Ogbobine sọ pe gẹgẹ bi ẹri ti o wa niwaju ile ẹjọ, Idubor ni Arẹmọkunrin Oloogbe na nitorina, ọkunrin na ni o ni ẹtọ lati role baba na, ki o si jẹ Magaji le gbogbo ebi na lori gẹgẹ bi iṣẹdale ilu Ibinni ti la a silẹ.

Adajọ na sọ pe, ẹri fi han pe Idubor ti fi igbakan ṣoju Oloogbe na nibi ẹjọ kan ti ninu eyi ti Baba wọn oloogbe Oloye Egumen paapaa si tọka si Idubor gẹgẹ bi Arẹmọkunrin oun.

Nitorina, Adajọ na sọ pe, Baba ti o bi wọn lo bi Idubor. Idubor ni Arẹmọkunrin Baba wọn, oun ni o lẹtọ lati jẹ Mogaji ile, ati lati joye ilu ti baba wọn fi silẹ gẹgẹ bi asa ilu Ibinni ti la a silẹ.

Irohin fi ye wa pe, nṣe ni Idubor fosoke nile ẹjọ ti o si kun fun ayọ. Wọọrọwọ ni a gbọ pe awọn ọmọ baba rẹ jade kuro nile ẹjọ na.


## Champion Naps

Awọn Naps wa yio bẹrẹ sii jade lati August 17 (ọsẹ kẹta). Fun 5 special draws fi N5 ranṣẹ.
Fun ayo mẹrin ti ngba mẹta lọsọọsẹ, fi Naira kan ati aadọta kọbọ ranṣẹ si:

Manager
Champion Naps
SW5/293, Maya St,
Fọkọ Area, Ibadan

For wk 2 --Niger No. 2


## Ijinle owe Yoruba

(Fun ẹniti nfẹ Ọgbọn, Oye, ati Imọ) (7)
lati ọwọ lawuyi ogunniran

61 "Bi mo ṣe e, taani yio bi mi",
"Ohun ti mo ba tẹ a si tẹ"
'Bi o ku, ko tan', l'opin.

62. B'eegun njẹbọ ka
Nwọn a f'aṣọ boju,
Bi paraka njese
Nwọn a wẹwu apo;
Ooṣa ko jẹ farahan l'ẹnikan,
Oju ni i ti ọmọ, ẹru ki i ba a.

63. Baale, Baale a bi eṣu l'ode,
Eyi ti ko l'eṣu l'ode
Ab'ọran eṣu lọran.

64. B'ojojo ba nṣe iwọfa
Nwọn a ni, o gbe iṣẹ rẹ de,
B'o ba nṣ'ọmọ olowo
Nwọn a ni ko rọju f'ata s'ẹnu.

65. B'olowo ba njẹ orogan
Ti iwọfa njẹ agunmatẹ,
Bi nwọn ba kọ ebe l'owurọ
Ẹsẹ ni nwọn yio fi tu u ka lalẹ.

66. B'ọmọ ba jagbọn kiku,
Iya rẹ a jagbọn gbigbe e lọ si pado lọọ sin.

67. Babalawo a ku
Oniṣegun a rọrun
Adahunṣe ko ni i gbe'lẹ

68. Bọmọde ko ba ku
Yio jẹran t'o terin

69. B'ọmọ ko jọ ṣokoto
Yio jọ kijipa,
Eni bi ni l'a a jọ

70. Bi a l'ogun ẹru
Ti a l'ọgbọn iwọfa,
Ọmọ ẹni l'ere ẹni.




# Obinrin l'esu lẹhin Alagbara

## (5)

LATI ỌWỌ WOLI S. I. OWOẸYẸ

"EJO si wi fun Obinrin na pe, Ẹnyin ki yio ku iku kiku kan. Nitori Ọlọrun mọ pe, li ọjọ ti ẹnyin ba jẹ ninu rẹ, nigbana ni oju nyin yio la, Ẹnyin o si dabi Ọlọrun, ẹ o mọ rere ati buburu. Nigbati Obinrin na si ri i pe igi na dara ni jijẹ, ati pe o dun iwo, ati pe igi ti a ifẹ lati mu ni gbọn, o mu ninu eso rẹ o si jẹ, o si fi fun ọkọ rẹ pẹlu rẹ, oun si jẹ" Gẹnẹsisi 3, 4-6.

Bi Orilẹ-ede kan ba fẹẹ ṣubu ohun ti ko le ṣe Orilẹ-ede na ni anfani, ti ko si le mu Olori Orilẹ-ede na jẹ ẹni iyi ni eṣu yio maa fi siwaju Olori na.

Nipa bẹẹ, gbogbo enia Orilẹ-ede yio bẹrẹ si i gba ohun ti o lodi si ifẹ Ọlọrun l'aye; inu eṣu yio si maa dun nitoripe ninu eyi ni yio r'aye lo awọn arẹwa obinrin lati maa ṣi awọn olori l'ọna ki nwọn ma baa riran wo ọna otitọ.

Ani, bẹẹ gẹgẹ l'o maa nri fun Olori Ijọ, Olori ilu, Olori ile, ati Olori ile iṣẹ bi eṣu ba fẹẹ gbe wọn ṣubu.

Pataki irinṣẹ ti eṣu yio kọ na siwaju wọn ni "Owo". Eyi ni pe nwọn yio ri ọpọlọpọ owo. Lẹhin ti nwọn ba ti ri ọpọlọpọ owo tan ni eṣu yio waa maa tọka ibi ti nwọn yio maa lo owo na si ki nwọn baa le tete ṣubu.

Lẹsẹkẹsẹ ti nwọn ba ti ri owo tan ni eṣu yio waa gbe ẹwu igberaga wọ wọn.

Nigbati awọn enia ti a wi yi ba gbe ẹwu igberaga wọ tan, nwọn yio bọsode, nwọn yio si maa fi araa wọn han gẹgẹ bi enia pataki, ati gẹgẹ bi ẹni ti o gun igi, ti o si ti ri ẹhin aiye. !

Ninu hihu iru iwa bayi kiri ni awọn ara ile wọn yio ti di ọta fun wọn; nwọn yio si maa fi oju ọta wo gbogbb enia, awọn olootọ ni yio si maa fi oju buburu wo pe ọta oun ni nwọn iṣe.

Eṣu ni o nti wọn ti nwọn fi nṣe iru nkan bawọnyi. Eṣu l'o fọ wọn l'oju ti nwọn ko fi riran, eṣu l'o ra wọn ni iye ti nwọn ko fi le ronu lati mọ otitọ, o si gbe igberaga si wọn l'aiya ti nwọn fi nṣe afojudi si ẹni ti o le mu aiye wọn dara.

Nigbana ni nwọn ko nii gbele mọ, nigbana onjẹ ile yio di onjẹ aja l'oju rẹ, obinrin ile yio di ailaju l'oju rẹ. Nigbana ni eṣu yio waa maa juwe awọn ẹlẹyinju-ẹgẹ fun un.

Awọn ẹlẹyinju ẹgẹ wọnyi ni eṣu ti ko si ninu ṣaaju pe, gbogbo ti ba wọn sọrọ ni ki nwọn maa gba fun. Bayi ni eṣu ṣe maa nfi ẹwa ara obinrin ati ọrọ ẹnu wọn gbe alagbara ṣubu nibigbogbo ni orilẹ-ede aiye.

Irinṣẹ pataki ni obinrin jẹ fun eṣu, inu eṣu a si maa dun nitori eyi nitori nipa rẹ ni o ti fi fọ ọpọ ile, ọpọ ilu, ọpọ Ijọ, ọpọ orilẹ-ede, ti o si fi gbe ọpọ alagbara ṣubu.

Nigbati eṣu ba fẹẹ ba ile alagbara jẹ, yio da ija silẹ laarin oun ati iyawo rẹ. Nigbana ni yio maa juwe awọn ọmọbinrin ti eṣu ti le nile iya wọn fun un.

Nigbana ni alagbara yio maa gbe mọto rẹ lọ, yio si da a duro l'oju ọna lati fi gbe ọmọbinrin ti eṣu ti pese sibẹ de e.

Yio gbe ọmọbinrin yi sinu mọto rẹ, yio maa fun un ni imọran eke, onitọhun na yio si maa gba a wọle; kẹrẹkẹrẹ ọwọ wọn yio wọ ọwọ, ẹsẹ yio wọ ẹsẹ, ede araa wọn yio si maa ye araa wọu nitoripe eṣu kanna l'o nṣiṣẹ ninu wọn.

Bayi ni ọkunrin alagbara ati obinrin yi yio maa tẹle araa wọn kiri. Obinrin yio ko wọ alagbara l'oju, yio wọ ọ l'ọkan, yio wọ n'imu yio wọ ni ọpọlọ, yio si wọ ọ ni gbogbo ẹya araa rẹ! Ngbana ni obinrin yi yio gbe alagbara ṣubu!!

Njẹ ẹnyin ọmọ aiye yi ti nka iwaasu mi, njẹ ẹ ri arekereke eṣu? Ẹ ti mo irinṣẹ eṣu ti o fi mba aiye ja tabi ẹ ko mọ ọn?

Bawo ni a ha ṣe le bọ lọwọ iṣubu wọnyi? Ani, bawo ni eṣu ko ṣe ni i lagbara l'ori wa ninu ohun itanjẹ rẹ?

Ayafi ẹniti o ba pa oju ati ọkan rẹ mọ kuro ninu iwa agbere. O si daju pe eyi ko le ṣe iṣe laijẹ nipa agbara Adura ki a gba Ọlọrun ni Ọba laika ipo ati ọrọ aiye si nkankan.

Nitoripe bi a ba nronu ibẹrẹ aiye wa paapaa julọ, iṣubu ADAMU ninu Ọgba Eden o yẹ ki o mu wa mọ dajudaju ninu aiye yi pe ayafi ẹniti Oluwa ba pamọ l'o yọ ninu ewu obinrin ni ọrọ awa ọkunrin jẹ ninu aiye.

Nitorina, obinrin l'eṣu lẹhin alagbara, ẹ jẹ ki a ṣọra wa.

ADURA

Oluwa, jọwọ, ọrọ Rẹ ni mo gbọ yi, Njẹ mo bẹ Ọ; maṣe jẹ ki eti mi di si otitọ ọrọ Rẹ ki eṣu ma baa gba Ijọba Rẹ lọwọ mi. Oluwa, maṣe fi aiye ti a wa yi le Ejo aiyeraiye nni (eṣu) lọwọ. Oluwa, jọwọ fi Agbara ẸMI MIMỌ ra wa pada kuro ninu egun aletekọṣe lati ọdọ Adamu ati Efa, ki a le maa lo igbesi aiye titun ti yio ba Ọ jọba, Amin.



WOLI S. I. OWOẸYẸ
Oniwaasu naa



## IwE ORO OLORUN

Fun anfani ẹnyin ti o ṣoro fun lati ri iwe mi yi ra ni ọkọokan, mo ti ṣeto lati maa fi apapọ iwe na ṣọwọ si nyin ni aadota Kobo (50k) pere.

Awon Iwe na ni:

1. ADURA AIYERAIYE
2. IBANIWI OLUWA
3. KINI ILE AIYE ṢE BAJẸ?
4. Ẹ JỌWỌ ARA NYIN FUN OLUWA

Bi o ba ti fi Postal Order 50k ṣọwọ si mi, ng o fi apapọ iwe na ṣọwọ si ọ lagbara Oluwa. Fi owo ranṣẹ si:

Woli S. I. Owoẹye,
Box 1206,
Ibadan.


# Arinrinajo ku sori irin

Awọn Ọlọpa ilu Ikirun ti bẹrẹ si i fi imu finlẹ l'ori ki l'o fa iku ọkunrin ti nta oogun Oyinbo nilu Ikirun Ọgbẹni Kamọru Alamu Yesufu nigbati o nrin irinajo lati Ikirun lọ si Ọgbomọṣọ ni ọjọ kẹdọgbọn oṣu keje ọdun yi.

Irohin lati Ikirun fi ye wa pe ni ọjọ ti a wi yi gan an ni oloogbe na di ẹru oogun rẹ ti o nta mọ ara alupupu rẹ, o tamọ alupupu na, o si doriko ọna Ogbomọṣọ .

Ṣugbọn nṣe ni nwọn ba oku ọknnrin na ninu agbara ẹjẹ ti o rin oun ati oogun rẹ gbindingbindin .

Awọn Ọlọpa ti gbe oku ọkunrin na lọ si ile iwosan kekere (Cottage Hospital) ilu Edẹ fun ayẹwo. Iwadi Ọlọpa nlọ lọwọ l'ori ki l'o fa iṣẹlẹ na.

# ỌTI MEKUNNU NI OGOGORO

## —Faniran

ỌTI Ibilẹ ti nwọn nṣe ni ilẹ Naijia ti n npe ni "ogogoro" ki iṣe majele tabi ọti ti ko dara fun ara, niwọn igbati enia ba ti le maa mu un ni iwọntunwọnsi gẹgẹbi a ti iṣe fun ọti lile miran"

Eyi di mimọ nibi ayẹyẹ iñilọlẹ ẹgbẹ Niger'a Wine Distillers Co-operative Society Bẹiyẹrunka ti nwọn se ni Gbọngan Obisẹsan niluIbadan laipẹ yi l'abẹ alaga Alhaji A. Akanbi, ti ile iṣẹ Afara I-ofo, Associate Insurance Company. Ninu ọrọ rẹ, akọwe ẹgbẹ na, Ọgbẹni 'Leke Faniran fi ye awọn enia pe ọti ogogoro ki iṣe majele tabi ọti ti ko ba ara mu bi awọn ẹlomiran ti ro. O ṣalaye pe, ẹgbẹ oun ti ṣakitiyan pupọ l'ori ọti na lati iduntin wa lẹhin iwadi pẹlu awọn Ọjọgbọn ọmọ ilẹ Naijiria meji kan ni ile ẹkọ giga Yunifasiti ni Eko, o han gbangba si awọn pe, ọti t'o dara ni mimu ni ọti ogogoro iṣe eyiti awọn mẹkunnu si nmu pupọ ni ile Naijiria.

Ọgbẹni Faniran sọ pe idi niyi ti awọn fi darapọ mọ ẹgbẹ Alajọṣe ti Ipinlẹ Iwọ-Oorun ki awọn le moke ninu eto ati gbe iṣẹ ọti na kalẹ daradara.

Ṣaaju eyi, Akọwe ẹgbẹ na mẹnuba ete ati eto ẹgbẹ na, o si kesi awọn gbajumọ ọmọ ilu Ibadan ati awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ fun iranlọwọ ati ifọwọsowọpọ wọn l'ori eto ati maa ṣe ọti na ni ilẹ Naijiria eyiti awọn dawọle nisisiyi.

Lẹhinna ni awọn Alakoso ile iṣẹ Nigerian Distillers Associates, Ọjọgbọn S. O. Odeyemi ati T. O. Olubusi ti ile ẹkọ Yunifasiti Eko sọrọ. Nwọn ṣalaye nipa anfani nlanla ti yio wa fun ẹgbẹ ti o ba faramọ ile iṣẹ awọn, eyiti iṣe iya ẹgbẹ fun awọn oniṣowo ọti ogogoro ni ilẹ Naijiria.

Bakanna ni Onirohin fun Ẹgbẹ Alajọṣepọ, Ọgbẹni Yẹmi Akinyẹmi sọrọ l'ori ọna idẹra ti o maa nwa fun ẹgbẹ ti o ba darapọ mọ ẹgbẹ Alajọṣepọ ti Ipinlẹ Iwọ-Oorun, o si rọ awọn Oludari eto na lati fọwọsowọpọ ki iṣẹ na le yọri si rere.

Diẹ ninu awọn enia ti o wa sibi ayẹyẹ na ni: Akindeji Babatunde Alaga; Joseph Akinade, Akapo, Ọlaniyan Babatunde, Samuel Ọkẹ, Yinyinọla Ọjẹlabi, Belo Akanji, E. A. Oyerinde, Akọwe Adun ilu Trading Association, Bayọ Adigun ati Emmanuel Akinwande.



LEKE FANIRAN

# Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Owurọ

10,901 Waidi Azeez, Ibadan.
10,902 Abdul Rasaki Oduọla, Ibadan.
10,903 Joel Eluyinka, Ifẹ
10,904 Mọdiyu, Eko.
10,905 Dẹyinde Ogun- Ilẹṣa.
10,906 F. A. Oruṣara, Muṣin.
10,907 Ibraihim Ọmọniyi, Iree.
10,908 Jonathan Aina, Badagry.
10,909 Musiliu Alade, Shagamu.
10,910 Rasaki Ọlaitan, Kwara.
10,911 Tawa Ọnakọya, Ijẹbu-Odogbolu.
10,912 Jamiyu Ọnakọ- Ijẹbu-Odogbolu
10,913 D. O Akande, Ogbomọṣọ
10,914 John Iyinkanluka, Ilẹṣa.
10,915 Amos Ọjẹdiran, Eruwa.

FUN IGBEGA EDE ATI AṢA YORUBA DI

**Omo Egbe Imole Owuro**

(Iwe idi ọmọ Ẹgbẹ)

Orukọ rẹ ________________

Adirẹsi rẹ: ________________

Ọmọ ilu ti o jẹ ________________

Jawe yi ki o si poosu rẹ si
DOKUN AJADI
(Akọwe Ẹgbẹ)
P. M. B. 5230, Ibadan

# Idanwo Bibeli

1. Kini Jesu sọ nipa ọrọ Ọlọrun ?
2. Kini Peteru sọ nipa Ọrọ Ọlọrun ?
3. Kini Dafidi sọ nipa Ọrọ Ọlọrun ?
4. Kini Jona sọ nipa Ọrọ Ọlọrun ?
5. Kini Amos sọ nipa Ọrọ Ọlọrun ?
6. Kini Johanu sọ nipa Ọrọ Ọlọrun ?
7. Kini Hosea sọ nipa Ọrọ Ọlọrun ?
8. Kini Ezekieli sọ nipa Ọrọ Ọlọrun ?
9. Kini Jerimiah sọ nipa Ọrọ Ọlọrun ?
10. Kini a sọ fun ara Heberu nipa Ọrọ Ọlọrun ?

Ẹ tete fi idahun nyin pẹlu titọkasi Bibeli ranṣẹ si:

Jọṣua Karimu Kobiowu
(Onidanwo Bibeli)
Mapo Christ Church,
Box 3062,
Ibadan.

Lati Ọwọ Jọṣua Karimu Kobiowu

# YEKINI KOMO

IROHIN ko to afojuba ni ayẹyẹ ikọmọjade ọmọ titun ti Ọgbẹni Yẹkini Jimọ ti iṣe Oludari ile iṣẹ Tẹtẹ ti njẹ Iwalẹwa Pools House, Oke-Arẹ, Ibadan ṣe ni ile Agun ni adugbo Ọjagbo Ibadan ni ọjọ kẹta oṣu kẹjọ ọdun yi.

Orukọ ọmọ titnn na ti nwọn sọ gẹgẹbi ilana ẹsin Islam ni Aminatu Adukẹ. Iya ọmọ na ni Iyaafin Saratu Ajikẹ.

A gbọ pe nwọn nawonara l'ọjọ na; ọpọ enia l'o si wa sibẹ. Diẹ ninu wọn ni: Layiwọla, Lekan Ọladeji, R. Ọla-City, Iyaafin Dikatu, Rafiu Ogunjọbi, Lamidi Baba Yaya, Iyafin Mọladun Owofutu ati Tamiyu Ajadi Ikire.

# Jovial Nap

NAP 1, 11, 32

In Week 3, Q. P. R is at away on no 9, there is assurance of winning 5 Sure draws. Come personally to me with N10 Cash.

M. O. Oketọna
15 Oke Ọla St
Apomu -- Ikire
11xxbk

**32**

**27**

FOR WEEK 2

IWE IGBAẸLODE DARA PUPỌ

1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 10k
2. Kurani esu marun Yoruba 55k
Esu kan (25k)
3. Yasin ni Yoruba (15k)
4. Zabura ati itumọ (55k)
5. Zabura Yoruba (40k)
6. Iwe Aiye Akamara (50k)
Iwe Eniaṣoro (50k)
7. Adedẹwẹ (35k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (N3); Kekere (75k)
9. Iwe ala ni nla (N1.50)
10. Kekere (30k)
11. Iwe Oogun iwosan (N1.5k)
Kekere (45k)
12. Itan Anabi ati Yisa (55k)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (25k)

FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI:

(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a. Odoye Adeọyọ Rd, P. O. Box 3365, Mapo—Ibadan.



(2) Alufa Igbaẹlode, Mọṣalaṣi Idi-Iṣin St, Isalẹ Koto P. O. Box 17 Ilọrin.

## Omo Paakoyi kilo

EYI ni lati sọ fun gbogbo Musulumi Ogbomọṣọ pe, irọ patapata gbaa ni bi ẹnikan ba pe araa rẹ ni Olupitan bi ẹsin Imale ṣe wọ ilu Ogbomọṣọ yatọ si pe baba-baba wa ni o kọ jẹ Paakoyi kini nilu Ogbomọṣọ l'o mu Imọle wọ ilu yi.

Nitorina, a fẹ ki o ye gbogbo enia pe lẹhin awa ọmọ Paakoyi ti baba—baba wa mu Imale wọ ilu Ogbomọṣọ, ko tun si idile miran mọ ti o tun ni ẹtọ si oye Paakoyi ni jijẹ l'Ogbomọṣọ.

A si ni ẹri lati ile ẹjọ ti o gajulọ ni Ipinlẹ Iwọ-Oorun ati ọpọlọpọ awọn ẹri miran lati mu un da ni l'oju pe, idile Paakoyi tiwa nikan ni o ni ẹtọ si oye Paakoyi ni jijẹ.

Asalamin lekun waramatulahi wabarakatu.

Lati Ọwọ

Gbogbo Ọmọ Paakoyi l'akọlabo.

## Ikini

ẸBI Paul Agboọla'ati ti Oyebamiji Oyekunle, ki Arẹsa-Adu titun ti Irẹsa-Adu Ọba Oyedepo Ọladiipọ Ẹmiọlu fun ipo awọn baba rẹ ti o de. Ki ade pẹ l'ori ki bata pẹ l'ẹsẹ Ki igba rẹ tu onile alejo l'ara. Amin.



# Pools !

**Ojo Adisa Naps**

29 & 48, 39 & 40.
Fun 3 BKxxx ti mbọ ni WK 5, fi N5 ransẹ si Ojo Adisa, N4/273 Adeọyọ Oje Rd, Ibadan.
Next best 17

**46**

**Onje Ayo Tips**

**10**

**28**

**34**

# OLORIRE O ! OLORIRE O !!

AWA ẸGBẸ ONIṢOWO

## WESTERN NIGERIAN TECHNICAL COMPANY LIMITED

INU wa dun lati kede fuu gbogbo ẹnyin onibara wa nibigbogbo pe, iṣẹ ti awọn oṣiṣẹ wa dasilẹ fun ọsẹ mẹfa, eyi ti o mu ki iṣẹ ẹrọ riro duro ti de opin bayi. Iṣẹ ti bẹrẹ bayi, a si ti tun nrọ ẹrọ silẹ jaburata.

IWỌNYI ni iye ti a nta awọn ẹrọ na bayi, ṣugbọn a fẹ ki o ye nyin pe, nigbakigba ni a le fi owo kun owo awọn ẹrọ na gẹgẹbi awọn ohun elo ti a fi nrọ wọn ba ti ngbowo leri si.

| AWỌN ẸRỌ | IYE TI A NTA WỌN |
|---|---|
| Solo Lawn Mower | N195·00 |
| Solo Sprayer combi | N205·00 |
| Motan Combi Fog | N155·00 |
| Solo Chain Saw 30" 635 x blade x chain | N292·50 |
| Solo Water pump (2 hand) | N170·00 |
| Solo Electric Water pump (2 hand) | N120·00 |
| Water pumps leewe: | |
| WL 1500 with Ilo L 77 | N245·00 |
| WL 1500 with Electric moror | N211·00 |
| WL 2500 witn Ilo L 77 | N300·00 |
| WL 2500 with Electric motor | N300·00 |
| WL 5000 with Ilo L 101 | N475·00 |
| WL 5000 with electric motor | N475·00 |
| Circular saw bench 24" blade no motor | N340·00 |
| Circular saw bench 36" blade no motor | N600·00 |
| Blockmaking machine with spring 6"x9" x 18 | N180·00 |
| Blockmaking machine with spring 9"x 9"x 18 | N180·00 |
| Blockmaking machine with spring 2, $4\frac{1}{2}$ x 9" x 18 | N180·00 |
| Land creta blockmaking machine: | |
| $5\frac{1}{2}$ x $11\frac{1}{2}$ x 6 | N70·00 |
| 8" x$11\frac{1}{2}$ x 6 | N90·00 |
| Hand Block mould 9" x 9 x 18 | N75·00 |
| Gari Grater with Ilo L 101 | N325·00 |
| Palm kernel crackers with Ilo L 101 | N290·00 |
| Gari Frying pans | N155·00 |
| Becco Pepper grinding mill & electric motot | N190·00 |
| Becco pepper grinding mill & electric motor & Stock-fish | N210·00 |
| Becco pepper grinding mill & Ilo petrol engine & Stock-fish | N255·00 |
| Becco pepper grinding mill and Ilo petrol engine | N235·00 |
| Ilo petrol engine L 77 | N140·00 |
| Ilo petrol engine L 101 Rasul | N190·00 |
| Ilo petrol engine L 101 Rasul & R. Gear | N190·00 |
| Ilo petrol L 101 RRSF & Cent. clutch | N240·00 |
| 1. Single generators 4 KVA | N900·00 |
| Stock-fish table only on motor | N 30·00 |
| David cornmill and electric motor | N230·00 |
| David cornmill and Ilo Engine | N290·00 |
| E. Motor 1 Hp | N 97·00 |

TETE yara waa ra tirẹ l'oni ki o ma baa kabamọ. Maa bọ taara si:

**Western Nigerian Technical Company Limited,**

P. M. B. 5148; PHONE 22361/2
DUGBẸ ONIMATIRẸSI, IBADAN.

Printed and Published by The People's Star Press Ltd, N4/496B Yemetu Aladọrin P. M. B. 5230 Ibadan Olotu (Editor) Lawuyi Ogunniran